Owo
KIKA ... RUBO ... ARISE ... A ... ERU ... KAN

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LEJỌ

Asoje
Ejẹ ... eniyan ... wọn ko ... A ... Ọṣẹ ... doyika ...

VOL. XII. No. 895 LAGOS SATURDAY NOVEMBER 18. – NOVEMBER 24 1961. KỌBỌ MEJI (2D)


# EGBẸ ALAKUKO (N.C.N.C.) BORI NINU IDIBO ILA-ORUN ILE NIGERIA

Ninu idibo fun awọn enia ti y'o mu opo Ijoba ... Ila-orun ile Nigeria dani fun ọdun marun ... ti nwọn di ni ojọ Alamisi (Thursday) ojo ...-din-logun oṣu November yi, ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) ni o jagun molu ninu idibo na.

... ẹgbẹ, awọn enia mẹrin-din-ladọjọ ni ... yan n' ... Igbimọ Aṣofin—N.C.N.C. ti ni 98, Action Group 11, Dynamic Party 5, Independent 19. ... ku 13 ki awọn ka ibo wọn.

... gbẹgbe lati sọ wipe Dokita Chike Obi ... ẹgbẹ Dynamic Party wọle ni ilu re, ... Ọgbẹni E. O. Eyo ti o wa ni atimọle fun ... nibi ikede ibo wọle ni ilu re.

Nigbati ẹgbẹ Alakukọ ti si ... kọja ... ti bori, awọn ni yio si tun maa ṣe Ijọba Ila-Orun lọ fun ọdun marun miran.

## Alakoso Katanga Pahuda

Alakoso ijọba Katanga nilẹ Kongo, Moise Tshombe so wipe on ti ṣe tan lati ba Olotu ijọba Kongo patapata, ati pe on gba Ọgbẹni Joseph Kasavubu ni Alakoso ijọba Kongo.

# Alaiyeluwa Oba Obinrin Ilu Oyinbo Lo Be Ile Ghana Wo



Aworan ti a nwo yi ni ti Alaiyeluwa Ọba Obinrin ilu Oyinbo ti o wa bẹ ilu Ghana wo ni si'siyi pẹlu Ọlọlajulọ ọkọ rẹ.

Ṣeranwọgbe boroki ni igbadun abẹwo wọn na jẹ ni ilu Ghana. Ore pataki si ni ... Alakoso ile Ghana Kwame Nkrumah.

# ỌLỌPA RI KORỌFO ORI ENIA GBA

ABẸOKUTA - Awọn Ọlọpa sọ wipe won ri korofo ori enia kan gba ninu ile kan ni adugbo Itoko ni Abẹokuta.

Nwon ni ori na to ti enia ti o ti ku niwọn oṣu mefa sehin. Nwon si ti pe ọkunrin kan fun iwadi lenu re. Awon Ọlọpa se iwadi wo na nigbati nigbati nwon gbo pe nwon ti fọwọ ba oku enia kan ti o ti ku ni oṣu mefa sehin.

# BABA AGBA TO FE PA ARARE

EKO—Ọkunrin ag'alagba kan ti o to ẹni adọrin odun lọjọ ori re, ti o fẹ o arare pa ni ọjọ kan ti o gbiyanju lati bẹ s'oni latti ọri ke eni ti ẹkpa ramu, ni adajọ Kotu fi ranse si Ile Itọju awọn arugbo enia ti Ijẹba ni Yaba.

Baba na, Aiyu Ayode ni o sọ niwaju adajọ wipe ẹtit, ni on fẹ para on, nigbati on ro igbesi aiye on eo ti ko b,s, rara, ko si i,ẹ bẹni ko si ọmọ tabi ẹni ti le toju on, ni on se fẹ fi opin s, ẹmi on npa bẹ s'omi.

Adajọ se ikilọ funu, o si fi ranse si Ile Itọju awọn arugbo ti ijọba. Baba na sọ wipe on tun ṣẹṣẹ bẹrẹ aiye titun nisisyi, lẹhin adọrin ọdun.

## Orin Ero Radio Mu Obinrin Kan Fe Pa arare

IBADAN - Ọmobinrin adelebo kan ti oruko re nje ... Pẹrs, ti o ngbe atulu Acepo nitosi ilu Ibadan ri awon mu wa siwaju adajọ kotu fun esun wipe o gbiyanju lati pa arare.

Nigbati adajo bere lowo re wipe kilo ti je ti o fi fe pa ara re? o dahun wipe ero asoror agbesi (Radio) kan ti o wa nile aladugbo on ti oruko on k'ori, ti o mu on bi u lati pa ara on ki on mo se gbo kule oria be mo.

Awọn ọlọpa sọ wipe Angebrin na ọbẹ ge ọrun ara re ... kan nigbati o ngbe Mokọla ilu Ibadan ni ọjọ kerin oṣu November ọdun yi.

Adajọ ni ki awọn mu lọ si Ile Itọju awọn ti ori wọn yi (Mental Hospital) ni Aro, Abeokuta fun ayẹwo Oniṣegun.

## O le Nigba Enia Ti Oji Lile Pa

MEXICO - Irohin ti a ri gbo niti Oji lile kan ti o ja nilẹ Mexico ti o pa enia ti o le ni igba, ti o so ogogorun enia di alaini ile lori, ko si onje tabi omi mimu fun wọn.

Irohin ti a gbo so wipe oku enia meta-din-ladosan ni awon ri gbe nilu Nuzco nika soso, beni awon tun ri oku enia merin-le-ladona ni awon ilu agbegbe ile.

Nwon so wipe awon si ni ireti lati ri oku ilu miran ni agbegbe ibe, nitoripe awon ilu miran ti nkigbe fun iranlowo. Oni se ... jugbon awon ohun ọgbin ti baje pupo.

Lowo oji lile ari elun'mi, Oluwa rere gbaw


Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE

KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri ra nibikibi, ko si wọn, o mọ daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, ina-titan ati lati mã fi yánà Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!


# IYAWO DANA SUN ARA RE LAAYE

JAIPUR - Irohin Agbaiyesi ti a ri gbo ni wipe obinrin abileko kan ti ọko re ku, nigbati nwon ko igi jọ lati fi sun oku oko re nilu Jaipur, lapa Ariwa ile India ni enia bi edegberin ti nworan iyawo ti o dana sun ara rẹ ni aaye gẹgẹbi etutu ti awon Hindu ma nṣe ti oko obinrin ba ku,

Irufe etutu bayi je eyiti ijọba ti ko lati nkan bi odun s'ehin sugbon sibẹ sibe nwon ko ṣai nṣe ni ekokan.

(Wo yoku loju ewe karun)

# Itan Obinrin Kan Ati Eyie Agbigbo

Lati Owo S. Ola Amusa.

Ni igba kan, omo obinrin kan wa ti o je Otosi ywe'ni omo' irin yi ma nta jeun. Bo ti lo s ko ewe Ei ojo kan ti o te omo re si ebe igi ti on papa lo jere ewe ni jiji. O ja ewe o pe dada o wa ni on Ico lo wo omo on. Bi o ti de abe igi ti o gbe omo ni ko ri omo re mo.

O wa kigbe lohun rara pe ha! ta lo gbe mi? B ni eiye Agbigbo O wa nke, o ni ki eiye Agbigbo gbe omo on ko on. Eiye Agbigbo beere lowo re, o ni ti on ba fun ni owo mewa ki o fi omo fun on o ni se o lagba. Omo obinrin yi ni rara on ko fe Agbigbo tun bi lere pe ti on ba tun fi apoti aso mewa, ile nla, golu fadaka, wura, ati gbogbo nkan be.

Agbigbo ni se afun on lomo re kio kuro ninu ise to wa? kaka ki omobinrin yi so pe on gbo o so fun Agbigbo je gbogbo nkan to ka sile yi ko to omo on Nitori ti omo na ba dagba yo se nkan to ju yen fun on

Igbati Agbigbo gbo gbogbo alaye ti obinrin yi so O se lemeta, gbogbo nkan to ka sile lo ja de ati Eru to ma ru eru enia ja de. Eiye Agbigbo ba gbe omo obinrin na fun u.

Eru obinrin na dun to je pe on jo larin igba. Igba to ko gbogbo eru re dele tan ofun oko re ninu re Inu oko re dun dada. O fun iyawo re ninu re. Igba ti o fun ikeji re inu ikeji re ko dun rara. Bayi ni Iyale obinrin na ni on ylo se bi o ti se ko to di Olola.

( Wo yoku loju ewe kerin )

# Oloye Awolowo Yara Pada Wale

ABA - Oloye Obafemi Awolowo Asiwaju Ijo Alatako ninu ile Igbimo Apapoje da ikede iko ti o nse ni Ila-orun duro lati pada wa si ilu Eko fun ipade Igbimo nla ti nwon pe fun Alaruba (Wednesday) ojo kedogun osu yi.



Oloye Awolowo so fun awon Oniwe irohin wipe ise egbe Alasafere (AG) ni lati maa se itoju Iwe eto Ijoba, Asiwaju Ijo Alatako atata nilati ri aa wa ninu Igbimo nigbakigba ti nwon ba nfe se obunkohun ninu Iwe eto Ijoba. O so wipe Ijoba Apapoje ma npe ipade kankan si lala ni jeki awon Olugbimo mo ohun ti nwon fe se, o ni eyipe ki o di ekeu ti nwon npe ipe ipade be.




E Ma Se Fi Omi S'Ofo

E Ma Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe Okun Fun Irohin Ala dun.

O D'ARABA, KOSE GBE!

# ITAN GBAJUMA ATI OBA

lati owo F O Lassi

Ni igba kan, ọmọkunrin kan wa ti oruko rẹ nje "Gbajumọ ko wankan ti" ọmọkunrin yi pẹ pupọ ni arin ilu na. Ni ọjọ kan ọba gbọ oruko ọmọkunrin yi. O si ni ki wọn ba on pe ọkunrin na wa. nigbati ọmọkunrin na de ọdọ ọba, o dọbale o ki ọba, ọba ra i ki dara dara, Ọba si bi lere pe ṣe iwọ ni "Gbajumọ ko wa nkan ti ? o si ni bẹ ri Ọba si sọ fun pe ti iwọ ba le ri ẹiye akala mu wa fun on, y'o da ile ati ona on si meji, on yio fun yin ni apa kan ninu rẹ, ki ototo ọjọ meje (7) to de.

Ọmọkunrin yi si ni ko buru, o jade kuro l'ọdọ ọba, o si lọ wa ọpọlọpọ ẹgiri ra o uko ẹgiri na yoruba ama pe ni ogiri foeyin osi ko ori le igb nla kan nibi ti awọn ẹyẹ na pọ si, nigbati o de ibe o si mu ogiri ra fi pa gbogbo oju rẹ ati ọwọ rẹ mejeji, o si ṣe bi eni ti o ti sun ko pe na rara ni awọn ẹiyẹ yi gbọ orun ogiri ra wọn si sare de ibe lati yọ oju gbajumọ kan wa nkan ti je wọn si fo si ile ni ẹgbẹ ọmọkunrin yi bẹna ni ohe ẹkan ninu awọn ẹiyẹ na lese o si so fun ẹiyẹ na pe ọba ni oni ki on lọ mu ẹiyẹ akala wa fun on lati ri.

Ẹiyẹ akala si sọ fun pe ti wọn ba pa on oju atun ra ri, ti wọn ko ba si pa on oju atun tun ra ri, Nigbati wọn de ọdọ ọba osi fi han ọba pe ẹiyẹ akala na niyi, o si sọ fun ọba pe e kogbodọ pa ṣe ni ki ẹfi si ẹgbala yin lati ma sin ọba na sa gba bẹ wọn si fi ẹiye na si abala nigbati ọdun ori ọjọ keji ni eiye na si fo lo ọba si ti da ile ati ona re si meji o ti ko apa kan fun "gbajumọ ko wankna ti".

Gbajumọ ko wa nkan ti si dọlọla si arin ilu yi Ni ọjọ kan, arun ajakalẹ si bẹ si lẹ larin ilu yi, gbogbo wọn ni oju rẹ fọ tan. Ẹyẹ akala si fo de ibẹ lati wa yọ oju wọn lẹ o si de ọdọ Gbajumọ ko nwa nkan ti, o si ja ewe kan bayi, o si fi pa ni oju oju rẹ si la o tun de ọdọ ọba o si ṣe bẹ Gbajumọ ko nwa nkan ti ati ọba si dupẹ lọwọ ẹiyẹ Akala. Akala na si dupẹ lọwọ awọn mejeji o si sọ fun wọn pe ti ọba ti pa on ni ijọsi bayi ni oju yio se tun rari.

## E Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe

## Itan Obinrin Kan Ati Agbigbo

(O bẹrẹ lati ewe ...)

Bayi ni ikẹ... obinrin yi ... re ti o lọ si oko ewe ... de ... ni o ... duro ki Agbigbo le gbe ọmọ rẹ. Ope ... gbigbo de, ti ... si gbe ọmọ rẹ lọ igba to pe ... o gbe ju soke bẹ lori ọmọ re lọwọ Agbigbo Agbigbo tẹ ... low... re o ni ki lo nfe obinrin yi, o ni on nfe owo aṣọ gola ati feda ka, ati gbegbo ... n bẹ bọ ? Ẹye Agbigbo de lohun oni Inọ ... gbigbo nkan ... obinrin ni n bẹni

(Wo'y ka oju ewe keta...)

# ONISE OKO OFURUFU TI O JE OSERE BOLU



OGBENI Gordon West, ọmọ ibile ilu Oyinbo Gesi ni oje osise oko Ofurufu, ni o nse alafehinti (Goal keeper) egbe agbabolu ti nwọn npe ni Blackpool o si je ọmọ ọdun meta-din-logun

## Iyawo Dana Sun Ara Re Laaye

(O bere loju ewe keji)

Awon olosindu ni ig'agbo wipe ohun ti o to ti o si ye n fun iyawo ata'a ki o dana sun ara re l'aaye bi oko re ba ku ki ode orun le dara fun toko-t ya na.

Irohin yi wa lati abule Chitawa Chita nitosi Jaipur nile India.

## Itan Obinrin Kan Ati Eyie Agbigbo

(O bere loju ewe kerin)

Agbigbo so fun wipe iwo furan owo ju omo re lo. Bayi ni eiye Agbigbo bu obinrin yi to si so fun wipe o si lo ma taku ewo lo si ma ma ta jeun, O ni gbigbo ohun eso to wa lowo re di ofo lati oni Arisa ni yio ma ro kakiri, Eye Agbigbo ba fa omo re ya si wewe o ko fun u.

Inu obinrin yi baje ti o fi je pe ko le lo si ile mo.

Itan yi ko wa pe t wen ba fun ni kini kan kia gb tife tife.

## ABO IWADI IKU LUMUMBA

Awon Oluwadi ti Egbe Ajo jekeji agbaiye (U.N.O.) yan lati se iwadi iku Ogbeni Patrice Lumumba, Olotu akoko ti Ijoba ilu Kongo, gbe abo iwadi won na jade ni ojo Atalata (Tue day) ojo kerinla osu yi.

Nwon so wipe iku Lumumba mu ifura dani pupo si awon ara Belgium gegebi bi enire awon ni awon se ise jamba na gan-an.

Eniti awon toka si ni nwon npe ni Colonel Huyghe. Nwon so wipe iku Olotu ijoba Kongo je ohun ti awon ti pamopo le lori ati pe Captain Gat, ara ilu Belgium je okan pataki ninu jamba na.

Awon Oluwadi na so wipe iyato pupo ni o wa ninu oro Ijoba Katanga ti o so wipe awon ara ilu ni o pa Lumumba, Okito ati Mpolo nigbati awon nso lo kuro ninu igbekun.

Alakoso, Kasavubu ati awon isongbe re ni o fa Lumumba ati awon yoku ile ijoba Katanga lowo, nigbati awon ti mo tele wipe ota orun ko gb'ebo ni nwon fa won fun u.

Awon Oluwadi na so wipe eyiti awon fi han y yio jeki nwon tubo le se iwadi siwaju si atipe ofin yio le wa idi re laipe, gegebi oro won.

## ASOJU ILU SUDAN NILU OYINBO



Aworan ti a nwo yi, iti Ol la Sayed Amin Ahmed Husslin, ti ise Asoju ile Sudan ni o ngbo oro ti agogo nso nile ise kan nilu nla London, nibiti nwon ti nse agogo na s nu oro isoro fun ile Omdurman ati Khartoum.

Agogo na nso oro s'ko l'ede Larubawa.

## EJA PA ODE APEJA

EPE--Ode ap'eja kan ti oruko re nje Yinusa Momodu ni o lo si osa lo de eja, nigbati awo re mu eja Onida kan ti ida re gun to ese merin, nibiti o ti nfa eja na lati gbe sinu oko ni on pa subu sinu omi, ni on pelu eja onida woiya ja ninu awo re.

O gba ogbon enia to wakati meji ki awon to wakiti meji ki nwon to le fa awo ati eja Onida nla g'oke, nwon gbe Yinusa lo si Ile Iwosan ni Epe fun itoju sugbon ko pe kio to ku sibe fun oro ogbe ti eja na da si lara.

# KOTU DA ODE TO SESE LOWO RA SILE

ABEOKUTA - Okunri ag'e kan ti o tun nse ise ode a tebo ni Atule Odo Alimu t oruko re aje John Kemetu ti awon ti mbe rojo esun wipe o ti aiokita pa ode elegbe re Kaworise Fewode nipa yiyin nibo apo era ti clute ti ad jo Kotu Giga t'u Abeokuta d sile k o maa lo ni alafia.

Eleri o ta t t e j ri so ti Kotu wipe on pelu Kemetu t Olegle at awon d. miran ni a on jumo lo si o o ode ni u igbo Alumo ni Ijebu, ibe ni Kemetu ti y rb n fun eran atule ti o yo si awon ti o sep l ba enin o ku re.

O tun so wipe Olegbe ra ku ti oju - ona ki ki awon ti gbe de le iwosan, Kemetu far pu si fe ba yanty n pa ara re fun gegebi o ti kalara to ki awon ode to gba ibon kuro l o re. Esi ni ko mo-mo pa. Adajo da sile k o maa lo ni alafia.

## Atuko Ofurufu Ti Oba Obinrin



Oga'ko John Woodman, ti o tu oko ofurufu ti Alaiyeluwa Elizabeth Keji ati eko re wa lo si ilu Ghana ni ojo kesan osu yi fun abewo.

Oga'ko John Woodman bere si fo niru odun 1934, ninu odun 19.6 ni o di Oga'ko (Captain) l hin odun meji.

Advt 209

## Inland Waterways Department

NOTICE NO. 9/1961

It is promulgated for general information that the Lagos/Warri Creek Mail Service will not Call at Torofani after the 15th November, 1961, due to insufficient depth of water

(Sgd) E. A. Aileru
ACTING DIRECTOR,
INLAND WATERWAYS DEPARTMENT


# TERCO

## Ni

TAYA MOTO TI A TUNSE
Cn ni o darajulo nile Nigeria
-x- O NI AGBARA
-x- OWO RE ROJU
-x- OJA RE SI TA
O WA NI Sobu

# NIGER MOTORS

ODUNLAMI STREET, LAGOS.

# JOE ALLEN

TINUBU STREET, LAGOS.

## Faramobi Stores

NO. 60, KOSOKO STREET, 98 TOKUNBO ST, ati NO. 31, GREAT BRIDGE ST.
PHONE:- 23727 LAGOS NIGERIA

On ni awon Onibara ti o gbon ara.


## Nigerian Ports Authority

VACANCY - WORKS SUPERVISOR - DIVING INSTRUCTOR

Applications are invited from suitably qualified candidates for the post of Works Supervisor - Diving Instructor in the Engineering department of the Authority.

QUALIVICATION:

Preference will be given to persons who have been trained as a diver by Siebe Gorman, or Royal Navy.

DUTIES:

The Successful candidate should be able to demonstrate from an observation tank and instruct indigenous staff on diving operations, such as, placing and firing procedure in the use of underwater explosives, underwater air bolt firing, underwater flame cutting, welding drilling, concrete placing, fitting, carpentry and other craftsmen work required of a fully competent diver.

SALARY:

Scale 5: £1,350 x 56 - £1,686, plus £300 per anum overseas allowance where applicable, in addition to which there will be a diving allowance of £75 per annum.

METHOD OF APPLICATION:

Application on forms are obtainable from the personnel Manager, Nigerian Ports Authority, Apapa Dockyard, and should be completed and returned so as to reach him not later than 15th of December, 1961. Candidates in the service of the Government or a Corporation must submit their applications through their Heads of Departments who will forward same to the Pesonnel Manager along with Confidential Reports. Persons without requisite qualification and experience need not apply.

N.P.A. Notice NO. 648
14th November, 1961.

**Bayo Kehinde**
Secretary to the Authority

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P. O.Box 467 Phone No 23370.